# ÀDÚRÀ LÁTI DÁ WỌN DÚRÓ KÍ WỌ́N TÓ DÁ Ọ DÚRÓ

Bíbélì Kíkà: Ẹsteri 7/Ìjẹ́wọ́: Deut. 33:27

1. Ẹnikẹ́ni tí ó ń retí ìkéde ikú mi, kí wọ́n ó kú dípò mi, ní Orúkọ Jesu.
2. Agbára-kágbára tí ẹ ń ṣètò láti gbé májèle fún mi jẹ, ẹ gbé májèle yín jẹ kí ẹ sì dòkú dípò mi, ní Orúkọ Jesu.
3. Gbogbo agbára isà-òkú tí ń sọ̀rọ̀ ikú lórí ayé mi, ẹ dòkú pátápátá, ní Orúkọ Jesu.
4. Agbára ìṣe-àjẹ́ tí ń fi ẹ̀mí ikú pọ́n ayé mi lójú, ẹ dòkú, ní Orúkọ Jesu.
5. Gbogbo alénimádẹ̀yìn olóríkunkun ayé mi, ẹ pẹ̀yìndà, kí ẹ sì ṣègbé sínú òkun-pupa yín, ní Orúkọ Jesu.
6. Gbogbo ẹranko búburú tí ń lépa láti jẹ ayé mi run, ẹ sáré wọ inú ìparun òjijì, ní Orúkọ Jesu.
7. Ọkùnrin alágbára ikú tí ń wá ọ̀nà láti mú mi so fún pípa, pa ara rẹ dípò mi, ní Orúkọ Jesu.
8. Ẹnikẹ́ni tí ó gba iṣẹ́ láti pa mí ṣáájú ọjọ́ ayọ̀ mi, ni a óò gbésin láàyè, ní Orúkọ Jesu.
9. Ẹ̀yin ìkórajọpọ̀ tí wọ́n bẹ̀ lọ́wẹ̀ láti pa èmi àti ìdílé mi run, ẹ pa àwọn tí wọ́n rán yín níṣẹ́ run, ní Orúkọ Jesu.
10. Gbogbo àmì ikú tí ọ̀tá fi sí mi lára, Ẹ̀jẹ̀ Jesu wẹ̀ wọ́n dànù, ní Orúkọ Jesu.
11. Gẹ́gẹ́ bí ó ti rí fún Hamani, àwọn ọ̀tá mi yóò kú dípò mi, ní Orúkọ Jesu.
12. Ẹnikẹ́ni tí ó fẹ́ kí èmi ó kú ṣáájú ìgbà tèmi, àwọn ni yóò kú ṣáájú ìgbà tiwọn, ní Orúkọ Jesu.
13. Olúwa san án padà fún àwọn ọ̀tá mi gẹ́gẹ́bí ohun gbogbo tí wọ́n ti ṣe lòdì sí ìwàláàyè mi, ní Orúkọ Jesu.
14. Olúwa, fi àánú rẹ já mi gbà kúrò lọ́wọ́ àwọn tí wọ́n ń wá ikú mi, ní Orúkọ Jesu.
15. Àwọn ọ̀tá mi tìkárawọn ni yóò dípò mi láàárín àwọn tí òkùnkùn ti ṣe ìdájọ́ ikú fún, ní Orúkọ Jesu.
16. Ẹ̀yin agbára tí ń lu agogo ikú lé mi lórí, ẹ ṣubú lulẹ̀ kí ẹ sì dòkú, ní Orúkọ Jesu.
17. Ẹ̀yin agbára tí ń rán aṣọ ìsìnkú fún mi, ẹ kú kí a sì fi aṣọ búburú yín sìnkú yín, ní Orúkọ Jesu.
18. Ẹ̀mí Mímọ́ ò! já gbogbo ṣẹkẹ́ṣẹkẹ̀ dànù tí ń wọ́ mi lọ sínú pósí, ní Orúkọ Jesu.
19. Agbára-kágbára tí ń pè mí lọ sí alákeji, kú dípò mi, ní Orúkọ Jesu.
20. Gbogbo agbára tí ń lu agogo ikú lé mi lórí, ẹ kú pẹ̀lú agogo yín, ní Orúkọ Jesu.
21. Gbogbo ìgbìyànjú ikú àìtọ́jọ́ lòdì sí mi, àwọn olùṣe-búburú ni kí ó pa, ní Orúkọ Jesu.